The Hon the Chief Secy 105/

# EKO AKETE.

IWE IROHIN OSOSE.

ỌRỌ IFOJUSUN:—
"EMI YIO FI OHUN TI O NDUN MAKUNNU HAN AWON ALAGBARA, NGO SI JE ALAGBAWI AWON ODI".—W. T. STEAD.

VOL I. No. 27. SATURDAY, JANUARY 13, 1923. FOURPENCE.

*Editor & Proprietor*:—
ADEOYE DENIGA,
*Office*: 24, Williams Street,
P.O. Box 286,
Lagos, Nigeria.

ASAN-SILẸ NI OWO GBIGBA RẸ.

| | Eko. | Ilu miran ni Nigeria. | Ilu Okere. |
|---|---|---|---|
| Ọdun kan | 12/- | 13/- | 14/- |
| Oṣu mẹfa | 6/- | 6/6d. | 7/- |
| Oṣu mẹta | 3/- | 3/6d. | 4/- |

Ẹ fi owo ati *Letter* ranṣẹ si *Editor*.

## GBOHUN-GBOHUN.

### BI IYA NLA BA GBE NI ṢANLẸ, KEKEKE A MA GORI ẸNI.

Ọrọ yi lo bọ lẹnu wa nigbati a gbọ pe awọn ọlọpa ti Ijọba ni ki nwọn ma pin iwe ti Gomina Agba kọ ni ede Gẹsi ati ni tiwa nipasẹ titi-ilẹkun ọrọ ti Eleko, nfi Eleko ṣe yẹyẹ nigbati nwọn npin iwe na fun awọn enia ni *Monday* ọsẹ yi. A sọ pe nigbati awọn ọlọpa wọnyi de ita Ọbun-Eko pẹlu iwe na, nwọn kigbe lohun rara pe ki awọn ara ilu wa gba iwe ti Eleko ọba wọn yio fi gba ade lọdọ Ijọba!!! Oṣe! "Ojo to rọ lo jẹ ka ri koko idi agba!!!

### A-TI KEKERE MỌ "'ṢẸ."

Ọmọdekunrin kan ti orukọ rẹ njẹ EMAN ti a ro pe o ṣẹṣẹ jade ni Ile-iwe, lọ ṣe kọkọrọ aiye-deru kan, eyi ti o nlo lati ṣi awọn apoti bi mọkanle-ladọrin (71) apoti-alapoti, ti a nfi iwe awọn enia si ni Ile-ipinwe (*General Post Office*) ti o si nko awọn nkan ti ọwọ rẹ tẹ ninu wọn. Ṣugbọn ni *Thursday* ọjọ kẹrin oṣu yi, ogbole yi ba "onile nile" nwọn si ra a mu: awọn "akẹran" lọ tu ile rẹ nwọn si ri ọpọlọpọ iwe ati awọn nkanmiran ti ọlọṣa yi ti ji. Ẹjọ na si wa lọdọ awọn ọlọpa bi a ti nsọ yi.

Newspapers Edi/c - Editor

## ỌSẸ ADURA A-GBA-YIPO.

Pupọ Ile Isin ni nwọn ṣe Ọsẹ Adura a-gba-yipo ti ọdọdun ni ọsẹ yi: a si gbọ pe ninu awọn iya-afin ati awọn wundia wa ti nwọn lọ si Isin yi ko jafara ati "sa wu" ni gbogbo akoko na. Iyẹn ni o!!!

---

## AWỌN IJỌ BAPTIST AGBA "DA BETE."

Awọn Ijọ yi ṣe Ariya kan ninu gbangan Ile-iwe wọn ni *Sunday* ti o pari ọdun to koja: a gbọ pe "pa-pin" ni ere na: Alaga ọjọ na ni Eni-ọwọ J. Robbin Williams, awọn to ṣe e pataki ni awọn *Member* Ile-ẹkọ Ọjọ Isinmi ti *Church* na, ẹniti Olori wọn nṣe Ọgbẹni Amos. Ọpẹnibo (*Sunday School Superintendent*) Alakikanju ninu Isin Ọlọrun, ati Eru-jẹjẹ fun awọn ọsọlẹ: a ba Ọgbẹni yi ati awọn *Member* rẹ yọ si aṣeyẹ ọjọ na.

---

## Sir Hugh Clifford and Prince Eleko.

The reply of His Excellency the Governor to Mr. J. Egerton Shyngle in connection with the Petiton recently presented on behalf of the unfortunate Prince Eleko has created a great sensation in Lagos. While I personally regret his Excellency's decision I consider that decision definitive and irrevocable.

Although many people in Lagos just now are perplexed with doubt and misgiving, we must not forget the glorious services which Britain has rendered to the world and to civilisation. For over a century Britain has nobly upheld the cause of freedom; has waged innumerable wars in defence of weak and enslaved nationalities "Regions Cæsar never knew" have felt the benign influence of Britain. Spain, Portugal, the Isles of Greece, Poland, Hungary, Italy, Bulgaria, Egypt, Turkey the Coast of Guinea, the West Indies, the revolted colonies of Spain in South America including Mexico—all these ow deep debt of gratitude to Britain's emancipating power.

Britain's heavy sacrifices during the Great War on behalf of France and Belgium and Italy need not be mentioned. Through their sacrifices the most formidable military power on earth was eventually crushed.

"Regions Cæsar never knew,
Thy posterity shall sway;
Where his eagles never flew,
More invincible as they."

I extend my hearty sympathy to Prince Eleko, in the disaster which has befallen him, let him think of "The man of Sorrows and acquainted with grief. "Life is full of accidents, and if we believe in Jesus Christ Life's accidents must fade away into insignificance.

MOSES DA ROCHA
*M.B. (Edin.)*

---

## AṢA ATI ISIN ILẸ WA.

A gbidanwo lati fihan ni l'ẹnu oṣu diẹ sẹhin ibi ti a nṣe iran wa gẹgẹ bi enia dudu ti iwọ orun Afrika nipa riro awọn aṣa ati isin wa ti nigbati a ba ti mọ iwe; ko si ohun ti o di onişango, tabi on'ifa lọwọ ki o ma ṣe mọ iwe jayi tobẹ ti yio fi le tun awọn isin wọnyi ṣe ki o le ba ode isisiyi mu.

Ẹ gbọ ninu ara ọrọ iyanju ti Bishop ile Agahyin sọ nipa pipa aṣa ilu eni mọ, nigbati gb MANCHE KOJO ABABIO lọ ṣe isin idupẹ. Ọrọ t o mu fun iwasu nijọ na wa ninu Peter kini, ori kẹ ẹsẹ kẹsan—"Mo gba yin tọkantọkan loni l'oruk *Church* ti *England*. Mo gbagbọ pe ẹ wa lati s bi agbara nyin ti mọ lati ṣe iṣẹ nyin ati lati dupe fun Elẹda wa, tabi ni ọrọ kan ṣoki, si Baba w ti mbẹ l'ọrun, diẹ ni mo mọ nipa aṣa ati iṣẹdal awọn enia nyin, ṣugbọn mo ngbidanwo lati mọ si o si damiloju pe rere ni ẹ nṣe ti ẹ ntẹle aṣa a iṣẹdalẹ nyin. Awọn kan wa ti nwọn sọ p ilọsiwaju lẹ pe ki a ko ti lailai junu, ki a fi pa titun, o damiloju pe iṣina leyi, bi a ba si tẹ le nkan a bajẹ. A ni lati mu ti lailai lọ sinu titu

Nko sọ pe gbogbo ohun ti o ba jẹ mọ ti lailai la ni lati ma ṣe. Iyatọ ni lati wa larin nkan lapakan, ati lapakeji nipa ṣiṣe nkan na. Ipilẹ ohun gbogbo ti o wa laiye daradara ni.

Ohun ti o njẹ Ilọsiwaju ni ki a ma fi oju ọtun wo otitọ ti lailai.

O damiloju pe a ni lati dupẹ fun ọwọ ti awọn ara ilu yi nbu fun aṣa lailai, mo si gbagbọ pe iwa awọn ti o nfẹ ba aṣa lailai jẹ, jẹ eyiti o lewu fun ẹgbẹ. Ọkan ninu eredi ti a fi npa aṣa atọwọdọwọ awọn agba mọ ni pe awọn baba nla wa lo ti nṣe wọn."

Ninu iwe irohin *Gold Coast Leader* ọdọmọkọnrin ilu Aganyin kan ti o nkọ iṣẹ oniṣegun ni *Edinburgh* ni ilu oyinbo kọ iwe nipa ti nini ede ilu ẹni lati ma fi kọ iwe, o si sọ ọpọlọpọ ọrọ pẹlu ẹdun nipa pe awọn ẹlomiran ti nwọn ba jaja lọ kọ iwe ni ilu oyinbo ma nsọ pe awọn ko gbọ ede ilu wọn mọ, o ni on si ti ba ọpọlọpọ pade. Ninu awọn ọrọ ti ọdọmọkọnrin na sọ ni eyi :—

"L'ẹnu oṣu diẹ sẹhin ẹniti o nkọ iwe yi lọ s'ibi ere kan ti gbogbo agbaiye. Oniruru ilu ti o wa nibẹ jẹ mẹrindilọgbọn, awọn enia ti iwọ-orun ati ti iha Gusu Africa wa nibẹ pẹlu, apejọ yi jẹ ti ere, oniruru ilu si nkọ orin ilẹ wọn nikọkan ni ede wọn, nigbati a pe ara iwọ-orun Afrika ati ti iha Gusu rẹ lati kọ orin, awọn ti o ṣ'oju ilu wọnyi ko le kọ ikankan. Meji ninu wa kọ orin l'ede Gẹsi ati ti Faranse, ṣugbọn nwọn bi wa lere bi a ko ni ede, akọrin tabi olorin. Ẹniti o kọ iwe yi fi aye silẹ fun awọn ti o nka iwe yi lati ro fun'ra wọn esi wa."

## NATIVE JURISDICTION BILL.

Itumọ ti a le fun ofin ti a kọ si oke yi ni "ofin ati fi awọn enia dudu si ipo wọn." Ijọba ti ilu Aganyin lo gbe ofin na ju silẹ lati lo fun awọn ara ilu ibẹ, ṣugbọn nigbati a ti mu ofin yi lọ si inu ipade igbimọ aṣofin Ijọba, ni gbogbo ilu ti ṣi gangan pe iru ofin yi awọn ko ni fẹ. Bi awọn ti Ijọba yan gẹgẹ bi aṣoju ilu ni dudu ati funfun si inu igbimọ yi ti nja fitafita pe awọn ko ni gba, bẹ si ni ẹgbẹ gbogbo awọn ọba ilu Aganyin pàpà ṣe iwe si Ijọba pe iru ofin yi ko le wọ, nwọn si gba amofin ọlọla Hutton Mills Baba ẹgbẹ *Congress* lati lọ ja ija yi ni igbimọ aṣofin ti ijọba, awọn Loya ti ilu aganyin si parapọ nwọn gba Loya Awuna Renner lati fihan eredi rẹ ti ofin yi ko le dara fun ilu wọn. Bi gbogbo rẹ ti nṣe ranyin, bẹ si ni awọn iwe irohin wọn nke pẹlu ọpọlọpọ lakaye ti ko ṣe bi ṣubu pe ofin na ko dara. A dupẹ pe nigbati Ijọba ilu Aganyin papa ri pe gbogbo ilu lo dide si ofin na, nwọn mu ofin na kuro.

Ofin yi gun pupọ, o si jẹ ofin ti nwọn fẹ fi kaba awọn ara ilu Aganyin. Ninu ofin yi sọ pe Ilu ko le da Ọba tabi Ijoye yan laisi ọwọ Ijọba ninu rẹ, ati pe Ijọba le yọ Ọba tabi Ijoye ti ko ba gbọ ti Ijọba. Ilu Agayin kọ eyi patapata, nwọn ni yio sọ awọn Ọba ati Ijoye wọn di ti Ijọba, apa ko si ni ka wọn mọ. Irufẹ ofin yi ti gbogbo Ilu Aganyin kọ ni iwe irohin kan ni ki nwọn mu wa fun Nigeria.

## THE NATIONAL CONGRESS OF BRITISH WEST AFRICA.

A ri gbọ pe a o ṣe ipade gbogbo ẹka ẹgbẹ ti eniu dudu iwọ-orun Afrika ni ilu Saro ni ijokejidilọgbon oṣu yi, a o si bẹrẹ Ipade na pẹlu isin ọpẹ si Olorun. Gbogbo awọn ẹka ẹgbẹ na kakiri iwọ-orun afrika lo ti nmura wiriwiri ati lọ si ipade yi. A tilẹ tun gbọ pe Ebute Meta ti fi ọgọrun Pọnwun silẹ fun Ikọ tiwọn. Ewo ni ẹnyin ilu to ku nṣe? Ẹnikẹni ti o ba mọ iyi ire ti ẹgbẹ yi le ṣe fun iran wa yio gbidanwo ati lọwọ ninu iṣẹ ribiribi yi. Ọran gbogbo ilu ni ki iṣe ti ẹnikan. Ẹkẹta ti a o ṣe iru ipade bayi niyi, o si yẹ ki a ma jẹ ki *Nigeria* rẹhin. Awọn ikọ ti o ti lọ si iru ipade na ri niyi :—Alufa Campbell, Professor Deniga, lọ si ti ilu Aganyin, Oloye Onifila Funfun Oluwa, ati Ọgbẹni Shyngle olori Amofin *Nigeria* lọ si ti ilu oyinbo, ko ha yẹ ki a tun mura fun ti ilu Saro bi?

FANOKUN.

---

## ANFANI "EKO AKETE."

Eko Akete ti nsọ ọrọ nipa Ijẹbu Rẹmọ lọwọlọwọ yi, o to arun meji. Ekini, nipa ti ọna ti Gomina wa ẹni rere nmura lati la fun awọn Onimọto si Jẹbu Rẹmọ. Ekeji, nipa ohun rere ti a ko ni tanma pe o le ti ilu Ogere ni Jẹbu Rẹmọ jade wa.

O jẹ ohun iyari fun mi lọpọlọpọ nigbati mo ba ngbọ ọrọ nipa Jẹbu Rẹmọ Nitorina nipa ti ọrọ kini, mo ki Gomina Olufẹ wa Sir, Hugh Clifford lọpọlọpọ, mo si gbadura pe ki Ọlọrun fun ni Ẹmi gigun lati ma ṣe alabojuto wa pẹ titi. Bi on papa ti jẹ ẹni alafia, ki alafia Oluwa ko pọ fun. Gẹgẹ bi ẹniti o ni ifẹ si ọnakọna ti owo le ma fi pọ, nitorina ni ireti pe laipẹ Gomina wa yio si tun fiyesi lati ya ọna ọkọilẹ *Branch Railway* si Jẹbu Rẹmọ pẹlu, eyiti o le lọ lati Ibadan si Jẹbu Ode ati lati ibẹ lọ si Jẹbu Rẹmọ ati lati Jẹbu Rẹmọ wa si Abẹokuta tabi ibomiran to sunmọ Eko, ki ọkọ ilẹ na si le ma kọja ni awọn ileto Ijẹbu ati Ẹgba ni t'alọ t'abọ nigbana yio daju pe awọn Ekurọ ati Epo igbo Ijẹbu ki yio tun sun ikasi mọ bẹni ẹgbagbeje ogunlọgọ enia to nrin lọna Ijẹbu t'osan t'oru yio yọ lati ma ri ọkọ ilẹ wọ. Mo ṣe ajo ni o. nko to wi bẹ o, toto, mo juba Gomina alabojuto wa o; kabiyesi, ki Ọba ki pẹ o.

Nipa ẹsẹ keji ọrọ wa, pe nkan rere ti nti ileto ti a npe ni Ogere Jẹbu Rẹmọ jade wa, sa dakẹ? Iwọ ko mọ awọn Oniwasu Ajisọdidun bi awọn ẹni-ọwọ Oyekunle ti Ijọ *African Methodist*, ati ẹni-ọwọ Ṣopẹ.an ti awọn ẹya *African Salem* pe ọmọ bibi Ogere ni wọn dan? Ohun rere nitotọ ti nti Nazaeth jade wa, ọpọlọpọ ire tun nti Ogere nbọ. Ọlọrun ko fun wa ni ẹmi lati wo o. Mo juba Ade: Krisi o. Akarigbo ko pẹ o.

IBILE RẸMỌ.

## EKO AKETE.

Eko, Saturday January, 13, 1923.

### Ẹ KU ÀJÁ LÜ !!!

Fi ẹnipe kini a fi gege silẹ si ni, nigbati a fi kọ Iwe pataki wa ti inu Iwe-irohin yi ti ọsẹ to kọja nipasẹ ti ọrọ Eleko, ki Gudugbẹ Iwe Gomina Agba to ja lojiji ni ọjọ *Monday* ọsẹ yi, pe on ko tun gbọ ẹbẹ kọkan mọ nipa ọrọ na: gbukẹ ti iwe yi jade da pupọ enia lamu, kosi si ẹniti kika rẹ ko mu lomi; gidi pã, nigbati a ba ro orişirişi ọrọ işiri ti a ti ngbọ lọdọ awọn to jinlẹ ni ilu pe "Ifa fẹrẹ fọ 're" si Iwe-ẹbẹ nã na.

Ni tiwa, a dupẹ gidigidi lọwọ gbogbo enia ti nwọn ti nşe ayan ati wahala tọsantoru lati igbati ina ọrọ yi ti nru efi tu lati inu oşu *September* ni ọdun 1920, titi o fi di ina to njo bulabula loni: a si mọ pe Eşugbavi Eleko Ọmọ-alade tikalarẹ ko ni şai sọ bi Ilu ti duro ti on gbagba lati igbati ijangban yi ti de ba a: ko si ipa kan to ku ti Ilu ko sa tan lọkunrin, lobinrin, lọmọde, lagba, ni Kiriyo, ni Imale, ati ni Abọrisa, pe ki Gomina Agba le fi ori ji Eleko fun işişe yi, lẹkeji, şugbọn "pabo" ni.

Gẹgẹbi ọrọ na ti jẹ ẹlẹgẹ to, o wa ku sọwọ awọn Agbalagba Ilu, pẹlu awọn Idile Ọba ati awọn Oloye wa, lati mọ ewo ni şişe. Ẹnikẹni to ba fi pẹlẹpẹlẹ ka Esi Gomina yi, yio ri i kedere pe ọna miran bi ọdọ Ọba *King* ati ọdọ Sẹkitẹri Igberiko Ilu Gẹsi, Ọga awọn Gomina ti a ba ni ao tun şajo si, ti pin. Kosi ninu awọn ọrẹ to ti nka Iwe-Irohin wa yi lati igbati a ti bẹrẹ rẹ ti ki yio wipe awa papa sapa wa si ọna totọ pe ki ọrọ na le yọri si rere: a ko ro pe a fi eyi şe ete lẹşo ni.

Ọrọ to delẹ yi kuro ni fifi ọwọ-yẹpẹrẹ mu nitoripe ki i şe ọrọ oni bikoşe ti aiyeraiye. Ẹ jọ ki a pa ifẹ tabi mimọ-ti ara-ẹni-nikan ti sapakan, ka si kọju si eyiti a ro pe yio şe ilu Eko yi ni anfani lẹhin ọla nipasẹ ọrọ ti o diju yi: ti gbogbo wa ba pa imọ wa pọ si evi, gẹgẹbi ọlọgbọn enia ti ki yio ma ke abamọ titi si ohun ti awọn ALAGBARA sọ pe ko mọ 'yan lori mọ ayaşebi a tun mu ọna miran pọn patapata, a tanma pe irufẹ şişe bayi yio jasi rere ilu Eko wa yi, yio si mu idile Ọba wa ni Iga Idunganran duro şinşin, titi lai, nipa iranlọwọ Baba.

Awọn alagba oni-lakaye ni ilu, ni a mba sọ ọrọ tian-tian yi, ki şe awọn ọlọrun-lile, tabi awọn bole-bajẹ-ko-bajẹ-enia ti nwọn pọ larin wa ni nisisiyi to "wọbu."

Nitorina, ẹnyin olorukọ, ẹnyin agba Eko, ẹnyin idile Ọba, ẹnyin ONI FILA FUNFUN ti ẹ jẹ OLOYE fun wa, ati ẹnyin Giwa-giwa, a fi ọrọ banta-banta yi kọ nyin lọrun, o di' ọwọ nyin o, a-mulele; Ki ẹ ma şai tọ wa gbọnju ninu ọrọ na, ki ẹ ma si jẹ ki idile Ọba wa tabi fifi enia jẹ oye larin wa di piparun lakoko ti nyin, nitori ọrọ yi. Ilu ko şa nkere ko ma ni ãtàn.

AŞẸ WA NIWAJU O.

Ara ilu, a tun ki nyin lẹkansi, Ẹ ku ajalu !!!

"VESTA" SEWING MACHINES.

Nos. 3 and 4 Treadle on sale at No. 12 Odufẹgẹ Street, Ọbadina District Lagos.

At a giving-away price.

A call will convince you.

ALHAJI ỌLỌRUN-NI-MBẸ.

*General Trader.*

## ITAN ỌBA ADELE.

Nigba Ijọba Adele, o fi meji ninu awọn ẹru baba rẹ joye Ologun ti a npe ni Abagbọn ; orukọ awọn Ojoye meji na ni Aṣọgbọn ati Ọbajulai. Li akoko na, awọn ọba to ba jẹ nipo ọba to ku a ma gbe oku ọba to ku lọ sin ni Bini. Lati mu aṣẹ yi ṣẹ, Ọba Adele gbe oku baba rẹ Ologun , utere lọ sin ni Bini. Nigbati on ati awọn enia rẹ ngbe oku baba rẹ lo, Ẹṣilokun ẹgbọn rẹ to joye Ọlọja Ereko mo, o si ro pe bi Ọba Adele ba gbe oku baba rẹ de Bini, ti o ba si sin i nibẹ, yio gba agbara ati ọla lati ọhun wa, ati pe apa ki yio si ka a mọ, nitorina, o ranṣẹ abẹlẹ si awọn Iwẹrẹ, (eyini ni awọn Ṣẹkiri tabi Ijọ,) pe ki nwọn ma ṣe jẹ ki Ọba Adele gbe oku Ọba Ologun Kutere kọja odo lọ sin si Bini ; lati mu ifẹ Ẹṣilokun ṣẹ, awọn Iwẹrẹ fi ija fun Ọba Adele ninu ọkọ li agbami bi o ti ngbe oku baba rẹ lọ, nwọn si du u li ọna pupọ lati gba oku na li ọwọ rẹ. Ṣugbọn Ọba Adele ati awọn enia rẹ ko dakẹ, bẹni nwọn kọju ija gbigbona si awọn Iwẹrẹ tobẹ ti nwọn fi jagun lati owurọ titi di alẹ ; nwọn si simi. Li owurọ ọjọ keji Ọba Adele fi idiku pe awọn Iwẹrẹ wa si ọdọ rẹ, awọn Iwẹrẹ wa si ọdọ rẹ. Nigbana li o wa bi wọn pe tani ran wọn lati gbe ija si on bẹ ? nwọn si wi fun u pe Ṣokun li ẹniti o ran wọn, (awọn Iwẹrẹ darukọ Ṣokun nitori nwọn ko mọ Ẹṣilokun pe daradara.)

Ṣokun sa jasi aburo Ọba Ologun Kutere, oku ẹniti Ọba Adele ngbe lọ sin. Nitorina inu bi Ọba Adele pupọ lati gbọ pe orukọ Ṣokun li a da fun on. O pada lọ si ile ti on ti oku baba rẹ. Ẹṣilokun ẹgbọn rẹ Ọlọja Ereko si wa pade rẹ li ọna ; o si bere lọwọ rẹ pe eṣe ti ko fi mu oku baba wọn de Bini ? Ọba Adele si jihin gbogbo on ti oju rẹ ri fun Ẹṣilokun, ati bi o ti jẹ pe Ṣokun li ẹniti o di ọtẹ na si on. Nigbati Ẹṣilokun gbọ eyi, o fi ami ibanujẹ han gidigidi, o si ṣe ileri fun Ọba Adele pe ni ọjọ na gan ni Ṣokun yio jade kuro ni ilu. Nwọn kọju ija si Ṣokun titi nwọn fi pa ọmọ rẹ ọkunrin akọbi ti njẹ Ọduntan. Inu Ṣokun si bajẹ pupọ nigbati o ri oku ọmọ rẹ nilẹ ; nitorina lo ṣe gegun wipe, li aimọwọ, li aimẹsẹ, a pa on li akọbi ọmokunrin : adabi ewurẹ ba ṣu imi funfun, bi adirẹ ba yin ẹyin dudu, ni ara Eko fi le dẹkun ara wọn ba ja ni ilẹ yi lailai. O si lọ si eti ebute, o si doju kọ ọsa ni Idumagbo, o si fi ara rẹ re wipe, bi on ba mọ idi ọran ti nwọn tori rẹ ditẹ si on, ki ibu ọsa maṣe di fun on koja, ṣugbọn bi on ko ba mọ idi ọran na, ki odo ọsa na maṣe aifi aiye fun on kọja; o si rin larin rẹ titi o fi de Ijẹdẹ li aiwọkọ.

Lẹhin ti Ṣokun ti lọ si Ijẹdẹ, o wa di mimọ fun awọn ara Eko pe Ẹṣilokun lo di ọtẹ na si Ọba Adele, ija nla si wa larin awọn mejeji. Ọba Adele sa ti nbọwọ fun ẹgbọn rẹ ri, ṣugbọn nigbati awọn Eko ri i pe o nwa ọna a ti ṣe e ni jamba lati ọwọ Ọpọlu ẹgbọn rẹ, nwọn kọ fun u ko ma tun tẹriba fun u mọ, nitoripe oye ọba ga ju gbogbo oye yoku lọ.

Li ọjọ kan, Ẹṣilokun wi fun awọn Eko pe, on nlọ bọ Egun iya on ni Ebute Iga. Nigbati o de ọhun, o fi ija fun awọn ara Eko ti nlọ na-ọja ni Korodu, o si kọ awọn Ijẹbu pe ki nwọn maṣe ta agbado fun awọn ara Eko mọ ; nitori eyi, awọn ara Eko gbe ogun si i, nwọn si le e lọ si Iṣẹri.

Li akoko kan, awọn ẹru Ọba Adele sọ fun u pe awọn nfẹ lati ma ṣẹ Egun, nitori ti o jasi oro ilu wọn. O si ṣe inudidun Ọba Adele, o si fi aye fun wọn. Lẹhin na Ọba Adele pe gbogbo awọn Ojoye ilu ati awọn Ogboni Ologun, o si sọ fun wọn ilipa ti ṣiṣẹ Egun. Ṣaju akoko Ijọba Adele, ko si Ọba Eko to ṣẹ Egun ri, nitorina awọn Eko kilọ fun Ọba Adele ki o maṣe ṣẹ Egun, ṣugbọn Ọba Adele kọ, o si ṣẹ Egun o si mu Egun rẹ jade pẹlu, eyi si mu awọn Eko binu si i gidigidi. Lẹhin na wọn ranṣẹ si Ẹṣilokun ẹgbọn rẹ ni Iṣẹri pe ki o ma bọ wa ile. Nigbati Ẹṣilokun nbọ, Ọba Adele gbọ, o si ranṣẹ lọ sọ fun awọn Ojoye. Awọn Ojoye sọ fun u pe awọn ko le wipe ki ọmọ ma ṣe wa si ile baba rẹ ; bẹni Ẹṣilokun de si Eko, o si gunlẹ li ebute Alakoro, o si ti ibẹ lọ si Iga Idumata. Nigbati Ẹṣilokun wọ ilu tan, Ọba Adele fi ẹkun Ṣago Iyun kan ranṣẹ si awọn Eko ; nwọn gba a, nwọn si pa awọn Ilari rẹ meji ti o ran si wọn ; nwọn si ranṣẹ pe on papa si Iga Ojoye kan ti nwọn npe ni Ọṣodi ti ile rẹ koju si Iga Ọbajulai ; nigbati o de ibẹ, nwọn bọ bata ẹsẹ rẹ nwọn si fi gba a li oju, ṣugbọn ko sọrọ kan, o si pada lọ si ile. Ninu wọn si npete lati pa a, apakan si wipe ko tọ ki a pa Ọba. Pataki ọkan ninu awọn to wipe ko tọ ki a pa a ni Eletu Iwaṣẹ, on si ni baba nla Agoro Lagbokun.—*Iwe irohin Eko 1889.*

---

## EṢU Ṣ' ỌMỌKUNRIN TO FI SHYNGLE ṢERE !!!

Pẹlu ayọ ati inu didun ni a fi rohin pe a fi Ọgbẹni JOHN OLUWOLE GEORGE, ti Adajọ F. VAN DER MEULEN fi s'ẹwọn ọdun marun ni Abẹokuta nijelo silẹ ni anọ (*Friday*).

Awọn Adajọ mẹta lo dajọ rẹ ni Kotu (*Appeal*): Ọgbẹni J. EGERTON SHYNGLE, Lọya Jiga—Akere Koro Janjan lo ṣe ẹjọ yi fun Ọgbẹni na.

## ***Preachers for To-morrow.***

AWỌN ONIWASU ỌLA.

**ROMAN CATHOLIC (HOLY CROSS)**

Masses will be sung by Priests appointed.
Awọn Paddi ti a yan yi o ṣe Isin ni gbogbo akoko wọnyi. (MORNING)
Masses Isin Arọ.

6.30—7.30 8.30—9.30
7.30—8.30 9.30—10.30.

(EVENING.)

Masses (Benediction) Isin Ibukun.
4.45—5.30 6.45—7.30.

St. Michael's (Lafiaji.)

MORNING. 7 a.m.—8 a.m. 8.30 a.m.—9.30 a.m.
EVENNING. 5.45—6.30 p.m.

**ANGLICAN**

| Time. | Preacher. |
|---|---|
| 9 a.m.—Christ Church | The Vicar |
| 6.30 p.m. | do. do. |
| 9 a.m.—St. Paul's (Breadfruit) | Ven. Archdeacon T. A. J. Ogunbiyi |
| 6.30 p.m. | do do |
| 9. a.m.—St. John's (Arọlọya) | Rev. H. V. E. Johnson |
| 6.30 p.m. | do do |
| 9 a.m. & 4 p.m.-St. Peter's (Alapako) | Rev. J. A. Cole |
| 9 a.m. & 6.30 p.m.—Holy Trinity (Ebute Ero) | Rev. S. J. Gansallo. |
| 9 a.m....St. David's (Jordan) | Rev. J. A. Leigh |

**WESLEYAN**

| | |
|---|---|
| 10.30 a.m.—Tinubu | Rev. J Allen Angus |
| 7 p.m. | Rev. E. K. Ajai-Ajagbe |
| 10 30 a.m.—Ereko | Rev. A. N. Cole |
| 7 p.m. | Bro. S. O. Stowe |
| 10.30 a.m.—Olowogbowo | Rev. E. E. Williams |
| 7 p.m. | Rev. D. A. Beckley |
| 10.30 a.m.—Ọbun Eko | Bro. C. W. Faulkner-Shaw |
| 7 p.m. | Bro. Adebiyi Tepowa |

**AFRICAN (COMMUNION)**

| | |
|---|---|
| 9 a.m.—Jehovah Shalom | Rev. Supt. D. A Hughes |
| 7 p.m. | Rev. J. F. Oguuko |
| 9 a.m.—Bethel | Rev. E. A. Akiọla |
| 6.30 p.m. | Rev. J. W. Bara |
| 10.30 a.m.—African Methodist | Bro. L. A. Randle |
| 4.30 p.m. | Bro. A. T. Iroko |
| 9 a.m.—Ararọmi (Baptist) | Bro. J. F. Oṣodi |
| 4 p.m. | Bro. J. Apena |

**EBENEZER (BAPTIST)**

| | |
|---|---|
| 9 a.m. | Rev. A. A. Puddicombe |
| 6.30 p.m. | Rev. E. C. Alabi |

**BROTHERHOOD**

| | |
|---|---|
| 7.30 a.m.—Ilupesi | Bro. Fagbemi Faseyi |
| 7 p.m. | Pastor A. Adedeji Iṣọla |

**St. STEPHEN'S (EPETEDO)**

9 a.m. & 4 p.m. Very Rev. J. G. Campbell

**AHMADIA**

6 a.m.—Fajir Service Bro. Y. P. O. Ṣodẹinde
5.30 p.m.—Open Air Service Imam K. R. Ajoṣe
(Bamgboṣe Street.)

**COLONIAL CHURCH (ODAN)**

8 a.m.—Holy Communion Rev. H. A. Lewis
6.45 p.m.—Evensong and Sermon do

---

## BUTTER NYAJU!

Ohun jijẹ kan ti o na Butter jẹ ti a npe ni

"MAGARINE"

Ọlọja Agba Ayinrin

ti gbogbo enia nsure si, wa fun tita ni Ile awọn Oyinbo Oniṣowo,

STANDARD COMPANY OF NIGERIA LTD.

Ni Ibode lailai (Custom Street) L'Eko

Ṣile kan pere ni panu kọkan; o ṣe anfani ti a ba ko ni giri. Ọja na pọ to Iyẹpẹ, ṣugbọn bẹ lo ṣe ka-yin to.

Yara lọ ra tirẹ nibẹ, bi bẹkọ, afara nja ọ.

---

## ***Correspondence.***

The Editor, "Eko Akete," Lagos.

Sir,—The subjoined copy of Cablegram received from Moulvie A. R. Naryyar B.Phil., F.P.C. etc. who sailed homeward by the T.S.M.V. "Ada" which left here on 22nd December 1922, is forwarded you for favour of publication please.

It has been rumoured far and wide and firmly believed by many an ignorant folk that the humble and learned priest was dead on the way and found his grave under the gloomy sea. Our opponents and assailants have taken much pleasure in the contemptuous promulgation.

Yours very gratefully,

10/1/1923. Y. P. Oyeshile Shodeyinde.

Copy of Cablegram received at Lagos at 9.30 a.m from London Post Office on the 8th January 1923 at 12.10 p.m. addressed to Imam Ahmadia Lagos.

Arrived, prayerful.

NAYYAR

[Not until our local Legislature make the spreading of false and wicked news by **A CERTAIN CLASS OF LAZY DRONES,** in town an indictable offence punishable with fine and inprisonment, shall Lagos get rid of those good-for-nothing fellows whose sole object, it appears, is always to make one's hair stand on an end, by their unfounded and mendacious information.—ED. E.A.]

22, Apatira Street, and
34, Palm Church Street,
Lagos, 6th January. 1923.

I beg to inform the public in general that I am now a Headman of "Esu" in Lagos, for everybody who wishes to join same; it commences from 10/- to £5 every Calendar month from any one who wishes to join same; as long as you can subscribe it is only for six months, before you can receive your share and six pence will be my commission on £1. 0 0.

2. And another commences from 1/- to 10/- every week for any one who wishes to join the "Esu" for three months before you can receive your share and my commission will be six pence on £1 0 0.

3. I may bring to your knowledge again that if you keep long in "Esu" and you want some amount to use, I will help you before you finish your share.

4. I get a certain amount for it to start same, if anybody wishes to join this "Esu" he or she should see me at 22, Apatira Street. or 34, Palm Church Street, Lagos.

*Another due date for the above is 31st January 1923.*

ABUDU WABI BAJELA.

"VESTA"

Treadle Sewing Machines for sale at same address. Prices moderate.

---

ỌMỌ NI YIO ṢẸHIN DE Ẹ.

"Ewa wo" "POSI Alarabara"

Ile Igbẹhin lọdọ J. T. COLE,

Gbẹna-gbẹna ni ita 40, Ofin Canal,

Ihin ko to afojuba

A le gbani ni awin ti a ba san idaji owo.

---

EMANUEL J. ADE DAWODU

Tailor and Draper

27, Daddy Alaja Street,

Perfect Fittings Guaranteed.

NOTICE.

When replying advertisers, please mention "Eko Akete"

---

AKIYESI.

Ti ẹ ba fẹ lọ si ọdọ awọn ti o polowo ọja sinu Iwe-irohin yi, ẹ jare ẹ sọ pe ninu iwe-irohin Eko Akete ni ẹ ti ri ipolowo ọja na ka.

---

Ọgbẹni H. CAMPOS,

Onişowo ni 7, Campbell, Street L'Eko

ni wabiwọsi oniruru onjẹ-panu (*Provisions*) ni tita: Ṣẹrẹkẹ şin ni awọn Itan-Ẹlẹde (*Hams*) ti o ni: Ọti *Wine* ati awọn Ọti miran to ni nda ni l' ọrun:

Ẹ tete lọra ti nyin nibẹ; awọn Ile-ọja rẹ miran tun mbẹ ni 63, Ọdunlami Street ati 2, Onikẹpọ Street Ita Faji l'Eko

Ohun a jẹ lo mba ni lọ.

---

"EKO AKETE"

A le ri Iwe-Irohin yi ra lọdọ awọn Aşoju wa wọnyi.

LAGOS.

1. Ajenifuja Stores, 109 Broad Street.

VIDAL R. COLE.

IBADAN.

Ọgbẹni A. M. Suberu Santo's House, Gbagi Street.

ZARIA.

Ọgbẹni A. Ẹkundayọ Cole, Accounts Office.

---

Are you suffering from impotent sexual & nervous prostration and impaired vitality. Use Muiracithin pills and get instant relief. It makes a man a man. In short it will rejuvenate you, also unsurpassed remedy for female Neniasthenia. Disturbed menstruation, sterlity, etc., etc. Its effect is sure and permanent, in bottle of 50 pills 5/- in bottle of 100 pills 7/- are you a sufferer of that troublesome Asthma? Why dont you use Asthamacid and get rid of it at once, in bottle 5/6. These medicines are German preparations and always give satisfactory results.

"Ajenifuja" Store
P. O. Box 201 ;109

VIDAL R. COLE
Broad Street Lagos

## MERCHANTS AND TRADERS

*PLEASE READ AND ACT.*

Four Reasons why you should advertise in "Eko Akete" a popular Yoruba Weekly.

**(Published every Saturday.)**

1. Because it is the only Vernacular weekly newspaper published in Lagos for the benefit of all Yoruba reading public in British West Africa of which Nigeria forms no inconsiderable part.

2. Because any advertisements submitted are generally translated into Yoruba in a particularly fascinating style which cannot but attract many customers to your Establishment

3. Because Yoruba language, being spoken and read by a greater number of the people both here and abroad, stands the chance of making your advertisements in Eko Akete welcomed and appreciated by the masses.

4. Because any advertisements in the language of the people of the country are the best medium for profitable results at all times

For Rates, etc.,
Apply at P.O. Box, 286,
or at EKO AKETE Office,
24, Williams Street, Lagos.


## IWE IKEDE TI ILU, IGBIMỌ TI EKO.

Iwe Orukọ awọn to nvan Enia sinu Igbimọ yi.

A kede pe gẹgẹbi Ẹsẹ Kẹfa ti Ofin Igbimọ Eko ti a mọ bi "Munisipa" ti ọdun 1919, ti wi, ẹnikẹni le lọ yẹ Iwe-orukọ awọn ti nyan enia si Igbimọ yi wo ni Ile-iṣẹ Sẹkitẹri Igbimọ na fun ijọ mẹrinla lẹhin Akiyesi yi.

Ni Akoko yi, Ẹnikẹni le kọwe si Sẹkitẹri na pe ka fi orukọ on kun, tabi ka yọ kuro lẹhin ti oluwa rẹ ba ti kowe fi fi eredi nkan bẹ han si Sẹkitẹri.

A. W. S. RUMENS
Sẹkitẹri, Igbimọ Ilu.

Ọjọ karun oṣu January, 1923.


## MAṢINI TO NKẸ RIRI !!!

Ọgbẹni ARNOLD SCHLESINGER,

Jamani Onişowo ara Hamburg, ṣẹṣẹ şi awọn ojulowo Ẹrọ-Iranṣọ ti Ọlọwọ ti a npe ni "MUNDLOS" nIle-Ọja rẹ ni No. 7, Ita Labinjo leti Ita Williams l'Eko.

Awọn Maṣini wọnyi wa fun kiko giri ni owo pọ 9. Awọn Maṣini Mundlos wọnyi jẹ eyiti a ti npe ni "*Original Victoria*" ri, nwọn si ko ẹra kan ninu awọn Ẹrọ-Iranṣọ ti nwọn dara jọjọ: Nwọn ko kẹrẹ ninu awọn Maṣini atata ti ilu Jamani.

A o si fun ẹnikẹni to ba ra ninu wọn ni awọn eroja wọn wọnyi, awọn nkan bi,

*Hemming foot, Feller, Braider* ati *Trimmer*, awọn bi *Steamer, Ribbon binder, Qilter, Ruffler* ati *ribbon fastener*.

Ti iwọ ko ba le wa, kọwe ranṣẹ si Apoti-Ipin'we wọn ni Ile-Ipinwe, No. 459 l'Eko. A o si fi Iwe Aworan Maṣini na ṣọwọ si ọ.

Ẹ tete ranṣẹ, bi bẹkọ, Ẹran nyin yio bi Obukọ.

## FOR SALE.

One Royal "Enfield" Motor Cycle. L. 690.
In good and working condition.

**For Particulars**

Apply to Mr. S. A. CLAY, 1, Macaulay Street,
Or at 75, Odunfa Street, Lagos.

## Ẹ WA RA ỌPỌ ỌJA.

Ọgbẹni D. B. OṢUNTOLU, onişowo Ọlanrewaju ni ọpọlọpọ ọja fun tita ni Ṣabu rẹ ni No. 44. Balogun Street, l'Eko.

Ninu awọn ọja rẹ ni iwọnyi:—Ikoko taba, Carpets, Panu ikole, Aṣọ oniruru, Itẹkọ, Baranjẹ, Olowonyọ, Yọmini, (*Satten.*)

Ati orişirişi nkan atata miran, Ọja Ọgbẹni yi rọju o si lere ninu, ọpọku-oyọku ni.

Ẹ lọ ra ti nyin nibẹ.

## "O ṢE 'WỌ NI!" (FAIR WARNING)

Ọgbẹni A. W. Olukolu Onigbanjo to gba Aṣẹ ọdọ Ijọba *Nigeria*, nta orişirişi ọja ni Gbanjo, nile Gbanjo rẹ ni 2, Isalẹgangan Street, l'Eko.

O si nta ile ati ilẹ pẹlu.

Awọn ọjọ ọja-tita ni iwọnyi. Monday, ati Thursday, lagogo mẹta ọsan. Saturday, lagogo mẹsan arọ, lọsọsẹ. O ntete san owo ọja fun enia. Mu ọja rẹ lọ si bẹ.

---

**N. V. HANDELMATTSCHAPPIJ V. H.**

## J. F. SICK ati Awọn Ẹgbẹ.

No. 7, Ita Ibode lailai, l' eti *Glover Memorial Hall* (*Customs Street.*) EKO.

Awọn Oyinbo onişowo yi nranşẹ MAṢINI-ARANṢỌ ti a npe ni VESTA Nos. 1-4 t' ọlọwọ ati t' ẹlẹsẹ ni owo to rọju, a le fi iye-owo wọn han ẹnikẹni to ba lọ si Ile-Owo yi.

Nwọn mura tan lati ṣe adehun pataki pẹlu ẹnikẹni to ba fẹ ránşẹ Mejila tabi ju bẹ lọ ninu MAṢINI na.

Awọn Oyinbo yi nṣe orişirişi Ilẹkẹ alarabara, Nwọn si nranşẹ (*Cement*) ati panu kikọle to nipon, ati ẹja Abọmafọ ati orişirişi ọja.

Ilẹkun Ile awọn Oyinbo yi şi nigbakugba ti enia ba fẹ lati lọ ba wọn sọrọ AṢIRI nipa Owo. IROHIN KO TO AFOJUBA.

---

## Ile Ita Egbogi ti Macaulay.

(*Macaulay's Household Dispensary.*)

A nta orişirişi ogun Ilera ni Ile-ọja yi, to wa ni Popo-nla (*Broad Street,*) l' Eko ni owo pọ ọ.

Awọn Ogun bi Oku, Painkiller, Ogun Inarun, Ogun Lakuregbe, Ogun Kuruna, Ogun Aran to dara Ogun Ẹda, Ogun Arẹmọ.

Ọgbẹni S. A. Q. Macaulay ẹniti oni Ile-Egbogi yi jẹ ẹniti o gba Aṣẹ ogun pipo (*Certificated Dispenser.*) lọwọ Ijọba Nigeria.

Ẹ LỌ DAN A WO, Ogun rẹ jẹ bi idan.

## ILE OWO-ỌJA RIRANṢẸ TI AWỌN ẸGBẸ OYINBO C. F. HUTHCHINSON NI ILU OYINBO.

Ọgbẹni S. B. VINTURA, Aşoju awọn Ẹgbẹ Oyinbo yi mura tan lati ranşẹ awọn Ọja bi *Herbadashery* eyini ni Ṣẹda, Onini, Owu-Ṣẹda alarabara, Ohun-elo awọn Aranşọ, ati oniruru Ọja bawọnni lati ọdọ awọn Oyinbo rẹ ni Ilu Oyinbo ni owo pọ ọ.

Ọgbẹni na si ni awọn Akẹtẹ (*Felt*) Bata Funfun ati awọn nkan miran daradara pẹlu ni, tita ti owo wọn ko ta enia laiya.

Ẹ lọ dan a wo ni Ile-Owo rẹ ni Ita Tinubu, t' o kọjusi Kọtu, l' Eko.

---

## ỌGBẸNI DURO: THOMAS.

ONIṢOWO PATAKI.

Ti 55, Ita Faji, l'Eko, ni orişirişi Ọja to de fun u lati Ilu Germany fun tita: awọn nkan Awo abọmafọ, Cement, Akara, ati ọpọlọpọ ọja miran.

Ẹ lọ de ibẹ, Igbo-Akan 'mọpa ni ohun to ni.

Bi ẹ ba fẹ, ẹ kọwe si i, *Number* Apoti-Iwe rẹ ni Ile ipin iwe (*General Post Office*) ni 374. *Number* fifi-ẹrọ manamana ba a sọrọ (*Telephone*) ni 243.

## ỌGBẸNI J. C. VAUGHAN.

Ti Ile-Ọja Sheffield ni Ita Kakawa ati Ile-Ọja "*Excelsior*" ni Ita Agarawu, ni oniruru awọn ohun kikọle fun tita ni owo ọpọku-ọyọku.

O ti nṣowo Irin Iṣẹ lorişirişi lati adọta ọdun sẹhin titi di oni.

ATARI AJANAKU ni ỌGBẸNI na jẹ ninu awọn onişowo Irin Iṣẹ ni ilu Nigeria.

ỌKỌ tita wa ni owo pọ ọ.

## ILE EGBOGI IṢẸ OLODUMARE.

A şi ile Egbogi kan ti a npe ni Işẹ Olodumare si ọja Ọbun Eko ni ile kẹta si Iga Oloye Aromire. Nibẹ ni a le ri orişirişi iwosan fun oniruru aisan,

Ibaşe fun Orifiọ, Inurirun, Ẹda, Inarun, Aran Kinnişa, Ikọ, Ipa, Ọrẹrẹ, Ọşẹ Egbogi, Egbog Oju, ati awọn Oniruru ti a ko le to sihin tan

Rin de bẹ ki o wo o. Irohin ko to afojuba.
Iwọ ko tilẹ gbọ oruko rẹ ndan?
Iṣẹ Olodumare !!!

JOSHUA O. ADE: CRAIG,
*Alabojuto.*

## ALASE LEATHER FACTORY.

"ILE ALAWỌ."

Sole-Leather tanned in a most modern style and Upper-Leather prepared in all colours, namely :—Black, White, Red, Yellow and Green, are obtainable at very cheap prices.




Awọ Bata ni ọpọku ọyọku. Kọwe ṣọwọ yala ni ede Yoruba tabi ti Gẹsi pẹlu owo si:—

E. B. BEYIOKU-ALASẸ
108, Moloney Bridge St.
P. O. Box 368, Lagos, Nigeria.
*Telegrams* :—Alawọbata, EKO.

---

## F. BLACKBURN & Co.

Jẹ awọn Oyinbo oniṣowo ti nwọn ni ọpọlọpọ nkan atata ti ẹnu njẹ lorişirisi fun tita. Nwọn si ni awọn Aṣọ JOJO ni oniruru to tete nlọ ni 'lẹ.

Ẹ lọ ke si wọn ni Ile-owo wọn.

Ni 45, Marina, L'Eko.

---

Awọn AWO ati IFE jojo ti a sọ ni "Macaulay m' Oluwa m' Ọba." ṣẹṣẹ de fun tita lọdọ Ajibabi ni 89 Ita Apongbon l' Eko.
Irufẹ awo ati Ife yi ko wọpọ. Ẹ lọ ba orire nyin pade nibẹ. Kosi bo ti ri ni.

---

AWON ẸGBE OYINBO ONISOWO TI A NPE NI

## E. H. STEIN ARA HAMBURG.

NEUERWALL 16 18, GERMANY.

Jẹ Awọn onişowo ti Ilẹ enia dudu, nwọn ma nranṣẹ ọja fun ẹnikẹni to ba fẹ' ibaṣe ọja ti Ilu Gẹsi tabi ti awọn Ilu oyinbo miran ti o wa lagbegbe England ati Germany.

Nwọn si nba enia ta Ọja bi Epo tabi Ekurọ ti a ba fi ranṣẹ si wọn si Ilu awọn oyinbo *(Europe)* ni owo ti o jọ enia loju.

Ko si ewu kankan ni fi fi ọja-kọja ranṣẹ si wọn lati Eko tabi Ilu miran ni *Nigeria*.

Ki ẹnikẹni to ba fẹ ba awọn oyinbo yi ṣowo lọ ri tabi ki o kọwe si Aṣoju wọn nibi Ọgbẹni Karimu Kọtun ti ita Ọba Dosunmu No. 3, tabi ni ibi-iṣẹ rẹ *(Office)* ni Opopo-nla *(Broad Street.)* ati ni ibi-ifi Ọja pamọ si *(Forto-novo Market Store)* L' Eko.

Ẹnikẹni le kọwe ni ede Gẹsi, niti *German* tabi niti *French*.

Oruko adugbo awọn Oyinbo onişowo yi ni ede *Wire* ni STEINAFRIK. Hamburg.

---

## GIDIGBO! GIDIGBO!! HEYA.!!!



Awọn RECORDS to nkọrin lede YORUBA pọ to wọbu ni ile owo.

MANN POOLE & COMPANY LTD.,
8, TINUBU SQUARE, LAGOS.

Ki la ti nṣ' oku l' ọrun?
Ki la ti nṣ' ori nile Iku?
Tutu tabi Gbigbẹ?
Ọpọkuyọku si ni, wa ṣa eyi to wu ọ ni:—
8, TINUBU SQUARE, LAGOS.

PRINTED AT "TIKA-TORE" PRINTING WORKS, 20, MARKET STREET, LAGOS, AND PUBLISHED BY ADEOYE DENIGA AT 24, WILLIAMS STREET, LAGOS, WRITER AND LECTURER.